ILE AIYE TI JO FUN WA, OWO TITUN L'A NNA

Ogun Ita'ja

E Polowo oja yin sinu Iwe Irohin Eleti-Ofe, Kia L'oja o ta.

# ELETI OFE

A-NJU-WỌN KO SE WI L'EJO




VOL. X No. 572. ELETI - ỌFẸ LAGOS, SATURDAY, MAY 17, 1958 KỌBỌ MEJI (2d

## Ile Aiye Ti Jo Fun Wa, Owo Titun L'a Nna

Orin ti o jade lenu wa ni orin yi nigbati a gbo wipe owo titun mbo, alawo bi Elejo-aja, Elewuro ati Onikoko eyi ni wipe

Ile aiye ti jo fun wa,
Owo titun la nna,
Ko se mani l'a nlo.

Irohin aladun ti a ri gbo ki orin yi to jade ni wipe Oloye Okotie-Eboh ti fi owo si Iwe adehun pelu awon Onisowo kan nile Oyinbo lati te owo Korensi oni Ponn kan, sile mewa ati sile marun fun ile wa Nigeria nihin.

Iye owo ti nwon o koko te jade ti yio di lilo ni odun 1959 yio je £70,000,000. Ise nla ribi-ribi ni Oloye

(Wo yoku loju ewe kejo)

## Bale Oko-Ilu



Eniti a nwo ninu aworan yi ni Lord Mayor ti Manchester nilu Oyinbo ti a le pe ni "Balẹ ọkọ ilu" nile wa nibiyi, nibi ajọdun kini ti lio awon ọmọ akẹkọ ilẹ Ghana ṣe nilu Oyinbo fun ti Ominira ilu won.

Lord Mayor na ni a nwo ti o mba Omidan Mary Kote ọmọ ilu Sekondi nilẹ Ghana ati Adele Idris ti ilu Eko Nigeria sọrọ nibi ajọdun na.

Orisirisi iṣẹ ni awon akẹkọ na nkọ nilu Oyinbo.

## Ololajulo Nile Ise Ero



Prince Philip. Ọlọlajulọ ti iṣe ọkọ Alaiyeluwa Ọba Obinrin ilu Oyinbo Gẹsi ni a nwo ninu aworan yi pelu awon ọmọ akẹkọ meji Mark Awobode lati ilẹ Nigeria ati Agwadrudlah Awan lati ile Uganda.

Ọkan ninu awọn ọmọ akẹkọ sọ wipe bi Ọlọlajulọ Duke ti feran enia to, o n fere ma mọ wipe ọkọ Alaiyeluwa Ọba obinrin ni on mba sọrọ, nitoripe gbefẹ ni awọn nmu fanji oro aso gbodun. Lodun 1924 ni nwon da ile eko na sile (Chelsea College of Aeronautical and Mechanical Engineering) nilu London.

## Oga Olopa Kan Ku Iku Aburadi

Ọga Ọlọpọ kan eniti nwọn fun ni iwe wipe ki o fi ilu Umuahia sile ki o wa lọ bere Iṣe ni ilu Abakaleke ni awọn ebe re se awuye-wuye fun u lati fi han bi iṣẹ re ti dara fun won to. Nwọn yesi nwon si sọrọ iwuri sipa re ni ale ọjọ ti yio lọ ku ọla. Nwọn je nwọn mu olukuluku si tuka lọ sile re.

Ki ile ọjọ keji to mọ ti awọn ti o yesi lale ana wa ba ko eru lọ sidi mọto nigbati awon de ile re o ti di oku. Nwọn gbe oku re lo fun ayẹwo lati mọ kini ohun ti o fa sababi iku Ọga Ọlọpa na.

A gbọ wipe ara Aji ni Ọga ọlọpa na ni agbegbe ile Ọgu Lẹbia ti nwọn yẹwo tan yewo tan nwọn gbe oku re lọ sin nilu rẹ.

## Enia Mokanle-logun Ku Si Ona Meka

SUDAN A gbo irohin lati ona Meka wa wipe ninu awon ero ti o nlo se Hadji ni Meka lodunni o di awon Alhaji mokanlelogun ti o ku si oju ona. Arun ti a gbo wipe o se oniko iku awon enia na ni arun ako igbe orin, eyiti o pa die ninu won ni ilu kan ti a npe ni El-Obeid tobe ti nwon ni lati ti Korenti awon ero Meka na. Nigbati awon si tu won sile ti nwon de ile Khartoun ni Sudan, arun yi tun pa enia mesan.

A gbo wipe Ijoba ile Nigeria ti ran Onisegu oyinbo kan lo si be pelu orisirisi egbogi ti o le pana igbe orin. Ijoba Khartoun so pe, oruko awon Alhadji ti o ku na, ati ibiti nwon ti jade wa, koiti te wa lowo.

Ijoba Sudan ti fi edegbeta Poun lele lati ma fi se itoju awon enia na nibiti a gbe korontí won si. Dokita A. Jinadu ni Onisegun ti Ijoba ile Nigeria ran lati lo se itoju awon enia na ni El-Obeid.

## Omo Olodun Nyera Wo



Obinrin ti a nwo yi ni iyawo Okunrin gbajumo kan ti awon npe ni Ani-baba, ti o lo silu Oyinbo on pelu omo re ti o gbe dani yi lo jijo ba won lo kirun odun kekere nilu Oyinbo ninu Mosalasi Shaj Jeman ninu osu April.

Matthew Mbu ti o je Asoju ile wa nilu Oyinbo kole lo si Mosalasi Odun sugbon o ran Imale kan eniti oruko re nje Malam Gieri lo soju re.

Awon ilu ti o tun ba won lo si odun na ni awon Imale apa odo wa nihin ti apa ile Gabasi ti awon ara Malay ti ile India ati awon ara Pakistan.

## Bako Mbo Kiyele Nilu Oyinbo



Eniti a nwo ninu aworan yi ti o nfun awon eiyele Trafalgar ni onje ni okan ninu awon enia ti Ijoba fun ni ebun eko olofe fun osu mefa lati lo ko ise ero asoro-magbesi Oruko re ni Segun Bako.

Baba re ni Alufa Eni-owo A.J. Bako. Ninu ilewe CMS Grammar school ni Bako gbe ko iwe. Omode kekere ti o duro ti o nwo Bako yi je ore re omo Olopa ni o si feran Bako



# Ere Bolu Af'esegba Ni A feran Julo

EKO. Nigbati Alaiyeluwa Oba Adeniji Adele Keji gba awon ijọ elere bọlu afẹsẹgba tilu Oyinbo to wa bẹ wa wo nilu wa nihin ni alejo lọjọ Satide to koja na Alaiyeluwa ọba wa ni sọ wipe wiwa silẹ wa ti ẹ wa yi jẹ ayọ ati igberaga fun wa nitoripe wiwa yia bọ si asiko ti ilẹ wa nia yi nmumọ lati di Ominira gẹgẹbi Orilẹ ede.



ỌBA ADELE KEJI

Kabiyesi sọ wipe aiwọn nkan bi adọrin ọdun sẹhin ni awọn enia yin mu anfani ẹkọ iwe wa silẹ wa, ọkan ninu ẹkọ pataki ti awọn fi kọ wa ni wipe "Ninu aralile nikan ni a ti le ri ẹmi ẹkọ ati imọ" nipa bẹ nwọn fun wa ni ere idaraya ni orisirisi sugbọn ninu gbogbo ere idaraya wonyi ere bolu af'ẹsẹgba ni a fẹran julọ.

E Ma Ka Iwe Irohin Eleti-Ofe Ki E Si Ma Pelowo Oja Yin Sinu Re-

# Omo Orisa Ni Dada

Ọkan ninu awọn ọmọ Orisa ti a mbi ni Dada jẹ. Isami ti a fi nmọ ọmọ ti o ya Dada ni wipe irun ori rẹ yio ta kobi-kobi. Ki irun ori wọn to ta kobi-kobi bayi; ọmọ na yio ma fi gba gbogbo sokun, isijẹ wipe ohun kan se e. Bẹni bi ko ba nidi obinrin ko niẹ Kumọlu. Ohun ti o se ọmọ na ti o fi nsọku bẹ ni, nigbati Ojugboro orisa Dirun-dirun ba ndirun fun ọmọ na.

Ọmọ ti irun ori rẹ ba dikoko bayi; o ti di eriwọ wipe, ki ẹnikẹni mase fi oriya kan ori rẹ. Nitori rẹ, bi Dada ko lei a, o ni aburo ti o gboju. Iyẹn ni wipe, ẹnikẹni ti o ba afi tulasi ya irun ori Dada aradun ni yio pa oluwarẹ. Eyi ni ara orin ti awọn ma nkọ fun Dada nigbati o ba nsọkun tabi oriki Dada.

Dada awuru-yale yagi oko. Dada ma sọkun mọ ero Ajasẹ mbọ lọna fun fun mi l'ọwọ kan ota mọri. Inu ọja l'a nlọ, ero ọja paramọ. Dada ko iasọ enia l'asọ ti Dada da bora Olukugi ! konkoso kugi lala. Dada ! Dada ko ni ku, Dada ko ni run Dada ko ni fi Jesu silẹ ko tun lọ borisa, d a d e owo o Bandele, ẹra, ẹ r a, ẹra Bandele.

# Omo Ilewe Jare Esun Ajomogbe Ni Abeokuta

ABẸOKUTA. Ọmọkunrin kan, ọmọ ọdun mọkandilogun ti o nlọ si ilewe kan ni Abẹokuta ti awọn ọlọpa fi sun ẹsun wipe o ji ọmọbinrin kan gbe pamọ, orukọ ọmọ ti nwọn gbe pamọ na ni Muyibatu Adunni. Ninu kotu Ake ni nwọn ti se ẹjọ na.

Awọn ọlọpa sọ wipe, isẹ ni Iya Adunni ran ọmọ rẹ, ki ọmọkunrin na to daduro sugbọn ọmọbinrin na si rojọ wipe ọrẹ ọkunrin ni ọmọkunrin na na jẹ si on, awọn si ti wa pọ bẹ to iwọn ọdun meji. A ma wa si ọdọ on bẹni on na a si ma lọ sile ọdọ rẹ.

Lọjọ ti ọrọ yi sẹlẹ iya on ran on ni epo nigbati on si npada bọ nọ ni ọrẹ on ọkunrin si pe on wọle ibe ni ọrọ na ti di ijọgbọn.

Nigbati Adajọ gbọ ọrọ yi ko sile bere mọ bi ẹjọ tire o da ọmọde kunrin na sile o si ki o ma lọ bayi ni ọrọ na ba mupo.

# Alakoso Ijoba Apapose



KADUNA. Alakoso ijoba apapose (Federation Prime Minister) Alhadji Abubakar Tafawa Balewa, so fun awon onirohin nigbati o gunle sihin ninu oko Ofurufu wipe on wa ba Alakoso Ijoba Ariwa, Alhadji Ahmadu, Sardauna ilu Sokoto jiroro oro nipa ise ati oro iselu ni.

Nigbati o mba awon osise ijoba Ariwa soro o kilo fun won wipe ki nwon mase dasi oro iselu ki nwon mu ise won dani gegebi eto ti ijoba ba fe.

Awon ijinmi enia meta lo wa pade re nibudo oko ofurufu o si ti pada de si Eko ni ojo Monday.

E L E T I O F E
A-NJU-WON KO S8 WI L'BIO

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAM

28, Kosoko Street, Lagos "ELETI - OFE LAGOS"

P. O. Box 467 Phone 23370

VOL. X. NO. 572. LAGOS, SATURDAY MAY 17, 1958.

# Efufu Fe Ari Idi Adie

Gbangba d'ękun, kedere bęwo ni ti Ibo si nwon dį ulu Eket, iję to wa labę ijoba N. C. N. C. ilę Ibo, fi han fun enikeni ri gedegbe wipe awon enia ilu Eket ati agbegbe rę ko ni igbękęle si ijoba ilę Ibo mo, ijoba ti Dokita Azikiwe nse Alakoso rę (Prime Minister).

Lati ojo pipę ni a ti ma nsọ wipe ęgbę Alakoso (N. C. N. C.) ko muro, ki işe ęgbę to le mu wa kuro ninu igbekun alaga iru ti a nsin labę ijoba ilu miran ani ijoba awon Oyinbo Gęsi onine're, ti awa na fi le di ominira ninu ijoba ara wa. Nisisiyi ęfufu sę nfę beni idi adię yio ma farahan s'ode fun enikeni ri boti wu ki o pę to, ofito yio d'ogu, yio si le gedegbe.

Gęgębi gbogbo oni lakaye enia yio ti gba wipe irewesi ati abuku to mba ęgbe Alakoko (N.C.N.C.) şe npoju nipa iwa ainikan şe ologa-joga ti inu awon oloti ęgbe na ko pade pelu arawon ni ohun pataki ti ko le mu ese ęgbe duro. Gbogbo idibo igbimo ibile ti awon nşe ilie Iwo-Orun agbara-kaka ni a tun fi ngbo oruko ęgbe Alakoko.

Ę fire fun ęgbe Afenifere o ti gberi,
"Eke re ku" bi oro Baba.

# Imoran Fun Enyin Abiyamo

Enyin abiyamo ę wa ra OMORELA o dara pupo fun awon omode.

Ama je ki omode ri orun sun daradara o dara fun otutu, iko ati orişirişi arun miran ti o ma mba omode ja ni asiko ehin. Opolopo abiyamo lo ti lo egbogi yi fun omo won ti won si so wipe o dara pupo fun awon omode

OMORELA BABY MIXTURE
(Sile Meji Abo 2/6d Fun Igo Kan)

O wa Lodo
COMMERCIAL MEDICINE STORES
(Qualified Chemists)
10, VICTORIA STREET, LAGOS.

# Igbimo Oja Koko Tita



Awon enia nlanla ti a nwo ninu aworan yi ni igbimo awon Oyinbo Onikoko (Marketing & Expert).

Dje ninu awon igbimo na ti a le daruko ni Ogbeni A. H. Young adele Alaga Igbimo Ologbe Akeredolu Ale, akowe awon Agba Sir Sydney Phillipson, C M G Alaga Igbimo yi R A Croft, (Deputy Director) ati Ogunlogo awon enia ti a ko le daruko tan.

# Ojo Alawo-ro Ntesiwa-ju

OJO. Enikeni ti o ba mo ilu Ojo niwon ogun odun sehin bi o ba tun wade ibe nisisiyi yio ri ilosiwaju nlanla. Ninu Ojo loni, opolopo ni awon ohun enfani ti a ni bi Ilewe ile onibiriki ile igbejo ile alaisan ile Isura ile igbimo ile isin Mosalasi ati Şoşi ati omi ero.

Ohun ti o şe abuku ti ko ye ki o jebe ni ti ona moto ti o lo lati Eko si Apapa titi lo si Ojo Alaworo. Oju ona moto yi ko suwon rara. A fi eyi ke si Ogbeni Azu Onyekwere Work, Overseer lati bawa mojuto oju ona yi

Bakanna ni a tun ke si Ogbeni M A Dada Senior Sanitary Overseer lati bawa moju to ona ti awon ero ngba ona na ha pupo o ye ki o ma ogi ri si i lati jeki awon olaolu okan ye ona ti awon enia nrin lo si oja ki o fe to ese meji.

Oyeki Ogbeni J A Ogunnowo şe ni ohun pataki lati mu ki awon Oleko ilewe ma ko awon akeko gegebi ati şe nbawa. Ninu ilewe St Michael ni Ojo awa Eleti-Ofe gbadun won gegebi Olori ilewe na titun ile eko na şe eyi ni Ogbeni J O Olabuse ati awon Idowu meteta Ajiboye Olusile Oyesiku Akintola ati Ogbeni Wesu A ni ti a n dupe lowo Moses Erinle ti Ojo nipa imoran ti o fun wa a ri pe imoran na yio şe wa lore

# Talo Ye Ka Da Lare

Awon orę mata kan wa ni ilu kan, awon ore keri-kosun arawon tobe to fi je

We yoku loju ewe karun)

# Meta Ni Eya Yoruba

**E ya meta ni eya Yoruba. Gbogbo eya ti o ni abaja ninu ila oju re je iran Ile-ife. Eyiti o ni pele je iran si Egba ati ayiti o ni Idoko je iran si Ilorin eyiti ao tun fi kun ni Baramu ti o je iran si Tapa,**

## Iwe Si Sekiteri Ilu Ojo

Olotu,

Jowo gba mi laye lati fi iwe kekere yi ke si Ogbeni J. A. Ogunnowo nipa awon Agbe ile Awori ti o nfe ilosiwaju.

Kakiri ni gbogbo ile Yoruba, awon Agbe lo ni owo ju, sugbon eyi ko ri be nile awon Awori. Ise ati Koko ko le hu nile wa, sugb n a ni ile papa (Field) ti o je ogedegede yanrin ti a le fi gbin epa.

A nfe ki a da egbe Agbe kan sile ti ao ma pe ni Union of Awori Farmers Association ki ibujoko egbe na si wa ni Ilu Ojo.

Lehin ti a ba ti da egbe na sile tan ki Ogbeni Ogunnowo se iranlowo fun egbe na lati ya ogidinleje lodo Ijoba lati fi da oko epa na. Enití o ba ni oro lati so ki o ko iwe si Sadiku, c/o Eleti-Ofe 28 Kosoko Street Lagos.

## Talo Ye Ka Da Lare

(Obere 10ja ewe karin)

wipe ko si ohun ti enikan ninu won le ni ti awon yoku ko ni ni iru ukan na.

Lojo kan awon meteta nlo si arin ijo kan nigbati awon de ilu kan nile okere okan ninu won ri eiye kan lori igi ofi han awon meji yoku Okan ninu awon ore na si fi roba owo re pa eiye na beni, eiye ja lati ori igi bo sinu Kanga ore keta parapo o ko sinu Kanga o si yo eiye na jade.

Awon ore meteta wonyi wa bere si ba ara won ja lori emi ni yio mu eiye na iwo ni yio mu. Awon ara ilu na la won nija ti afi igbati olopa de'be. Ninu awon ore meteta wonyi eniti o ri eiye kole pa eniti o pa eiye kole yo jade ninu Kanga talo ye ki o mu eiye na?

Emi ni

J. A. Afolayan

Okerimi Otun Oro






Awon gbajumo enia gba wipe gegebi mo ti je oga ako ile, mo mo nkan ti awon enia fe, mo si le so wipe Oti Star ni onikeni feran ju.

O da mi loju, ko si enitio le m'oju kuro ninu adun Oti Star, mdara to ba ge, o si lagbara pelu. Tabi iwo yio tun fe si i?.

STAR



OTI STAR

l'o je eyiti odara ju! Beni Sammy Sparkle wi.

Awon ohun elo to darajulo



ni afise, Eso o ka barley to l'orun daradara ni a fi se Oti Star, awon enia ti o loye lori pupo l'o ngise Oti Star, omo, o si ni awo to yayi.

Oti Star npa orungbe; adun re ko si legbe.

# Ero Lọna Amerika



Ogbeni Okotie Eboh eniti o ti lọ si ile Amerika nipa ogidinlejẹ owo ti ijọba ile Nigeria fe ya lodo awon Inter-National Bank ni Amerika a gbọ pe nwọn ti pari eto nipa owo na, nwon si ti npada bo wa sile.

Ohun ti a gbo wipe awon fe fi owo na se ni, ona oko Reluwe lati ilu Jos titi lo de Maiduguri nile Boronu. Ni sise bayi, nwon rope onje yio tunbo po si nile Nigeria.

# Itan Oku Iya Oduduwa

(Apa Kerin)

Latigba na, ti ọmọ Ifẹ kan ba gbọ pe Ajantala mbọ nṣe ni yio salọ. Bena ni titi oni. Bi ohun kan ba le nwọn o wipe e pe Ajantala si, ohunkohun to ba ti le ju fun ealo Ajantala to ba wọn yanju re

76 Orunmila wa nibe nigbati Ajantala mu ejọ lọ sọdọ Oduduwa nipa ajodun ti awọn ọmọ Ife nṣe Nigbati Ajọdun tun ko awon omo Ife lo ye Ifa wo bi ajodun na yio ṣeṣe Orunmila fi ye wọn pe teru tọmọ ni ko jijọ se ajodun na ko ni si iku mo Nigbati awon si se gegebi Orunmila ti so fun wọn, latigbana wa titi di oni ko si iku mo beni ko si arun, ṣugbon Ajantala di eru jeje si gbogbo omo Ife On na ko si bimo titi ofi ṣekun re orun alakeji aremabọ.

87. Ẹiyẹ Akala ranṣe si Oduduwa wipe nigbati o ba di ọjọ mesan loni gbogbo awọn ẹiyẹ mbọ wa kọrin fun u nibi aisun ogoji ọjọ oku iya rẹ. Gbogbo oluknluku ẹiyẹ ti nlọ dọdọ wo ni afin Olugbo tabi Olu-igbo.

88. Ẹiyẹ Akala Ọṣin, Gunugun, Awodi, Aṣa Leke-leke, Idi, ati titi o fi kan awọn ẹiyẹ wẹwẹ bi Adan Adaba, Oriri, Atiala ati awọn bẹbẹ. Nwọn pin ara wọn si meji-meji.

89. Oriri ati Atiala ni awọn pin papọ ti y'o jijọ kọrin nibi oku iya Oduduwa. Iṣe agbede adodo ni eiyẹ Oriri nṣe bi enu eiye Atiala ti tobi ju gbogbo ara rẹ lọ beni ti eiye Oriri pelu ṣugbọn oju wa nti eiye oriri lati gbe enu re nla yi yọju si awujọ enia eiye ati ọmọko nibi aisun oku iya Oduduwa beni gegebi nwọn ti yan a lati kọrin ko gbọdọ ṣe alailọ.

90. Oro ohun ti o le ṣe nipa ti enu na ko ri nigbati o se o wa to eiye Adan lọ o wi fun pe mo wa ninu awọn ti o nlọ kọrin nibi oku iya Oduduwa ni aisun ogoji ọjọ ṣugbọn enu mi yi tobi ju lati gbe yọju sibi aisun na nkorin ki o ba on gbenu na ku dẹ. ki o le se gbe fun on ise gbena-gbena (Carpenter) ni Adan nṣe.

91. Nigbati Adan gbe enu na tan o gbe e rekọja ala o sọ di rebete. Inu bi eiye Oriri si ẹyi ṣugbọn o dake ko fohun Adan na paapa ko mọ pe on tiṣẹ Oriri

92. Nigbati ọjọ ko lati lọ kọrin Oriri ko to yọju s'ode lati kọrin nitoripe enu re kere kosi ti mọ lilo re aisan kan wa nṣe eiye Adan aisan na ni pe bi o ba jeun tan nisisiyi bi o ba ti dide nṣe ni onje na yio gba furọ re bọ sile. O wa to Oriri lọ wipe enu furọ on tobi ju ki o ba on di furọ na ku diẹ. Inu Oriri dun lati gbesan

93. Nibi ase ogoji ọjọ nitoripe Adan yio ri onje je nibe o lo sọdo eiye Oriri o ni ko ba on di enu furo on ku gegebi o ti ti je pe ise agbede ni Ise Oriri nse lo kuku di enu furo re pa bamubamu

94. Nibi ase na ti eiye gbogbo tun nkọrin Oriri fo pere siwaju o wipe siwaju Adan lo gbe mi lenu fele-fele ti mo di furo re pi-pi pi. Lati ojo na wa ni Adan ko ti ni furọ mọ lati fi yagbe. Enu ti o fi njeun na lo fi nyagbe.

## AṢIWAJU IJỌ GODS' KINGDOM



Enia a nwo yi ni Ologbe Irobo ti o ti nse asiwaju ijo God's Kingdom on ni eniti o da egbe na sile. A gbo wipe Gods Kingdom je eka kan ti o ya kuro lara ijo Jehofa Witness, eyiti Ogbeni Brown ara ile Amerika mu wa sile yi. Laipe yi ni Egbe God's Kingdom tun sese bere si tesiwaju lehin iku G.D. Irobo ijo won na si ndi olokiki kakiri nisisiyi.


## Kere o!

Ati ni orisirisi ogun German to ṣeṣe de, fun onirurru aisan tokunrin tobinrin. Tete wa ra tirẹ ko to tan.

**J. A. AJAO BROTHERS**

MEDICINE STORES

7, Egerton Road, Lagos.



# PIRATE




Pali Titun Oni Siga Mewa Yi Ni O Sese Tun De

# Olabisi Ajala Pada Lona Irin Ajo Re

EKO. Ọgbeni Ọlabisi Ajala eniti o ti pinnu pe mọto olorente kan ni on yio fi rin irin ajo kari aiye. O ti de England ile Faranse ile Belgium Jamani Rosia Austria Swiss Italy Spanish Algeria Daka Saro; Accra Dahomi a t i Lagos. Inu awọn obi rẹ dun lati tun fi oju ri Ọgbeni Arinrin-ajo na.

Lehin ti o ba awọn obi re gbe fun igba die Ajala sọ wipe on koiti de opin irin ajo on nitori on si fe de Fortlamy, Kenya Kongo Abyssinia Sudan Egypt Iraki India Japan ati Ṣaina. A si gbọ pe o ti bere irin ajo re ti ori-ẹkeji.

Irohin ti o kan wa nisisiyi ni wipe Ajala koiti rin jina lori irin ajo re apa keji ni igbati jamba ṣele si mọto rẹ tobe t i o nilati pada wa silu Eko.

Ọgbeni Ajala sọ pe on yio ba ọkọ oju omi lọ silu Italy. nibiti yio gbe ra mọto titun miran fun irin ajo na

## TỌKỌ-TAYA KU NI SURULERE

SURULERE. Ọkunrin Onigegun kan njẹ Ayẹni ni Surulere lojọ ti yio ṣiṣe buruku yi o ran awọn ọmọ re nisẹ lọ si Abule Ijeṣa beni aya i y a awọn ọmọ na ko da o mbe ni Idubale.

Ki awọn ọmọ n a t o pada de, o t i pokunso ninu ile o si tilẹkun mọri Nigbati awọn ọmọ pada de, nwọn k o r i ọna ba wo'le nṣe ni w ọ n y a ọgba k i nwọn t o ba ehinkule wọle. Nigbati nwọn ri ohun ti o ṣele nwọn l ọ ibosi looo.

Nigbati Awọn Ọlọpa de, nwọn b a ibọn Ṣakabula kan ninu ile nwọn ri oku iya awọn ọmọ na nwọn s i r i b a b a wọn ti o pokunso awọn o k u mejeji ṣ i m b e lọwọ Ijọba.

# Baba—Lafin Yio Wo Ile Yi Loni



Kabiyesi ! Alaiyeluwa Bello Gbadegẹsin Alafin Ọyọ yio wọ ilu Eko yi loni, a si gbọ wipe ko ni pe pupọ ki o to pada.

Ṣugbọn ki o to pada yio de ọdọ Alaiyeluwa Ọba Adele Keji ninu Afin re yio si de ibi pupọ ki o to lọ pada. Iro l'a ngbọ. Oju Ko t'Alafin.

# Agbala Esin Oba



Ile ti a nwo yi jẹ apakan ninu agbala afin oba Buckingham nibiti oba obinrin, Elizabeth Keji, gbe nso awọn esin re mo. A gbọ wipe awọn enia ni agbala lo sa Ọloko esin fun oba na.

## INU ODARAN "DUN" LATI PADA S'ẸWỌN

KANO. Ogbologbo apẹjewon ti oruko rẹ n j e Halibu Salawa l o lọ ji sọ igan kan g b e iodẹ awọn Oyinbo Kora nigboro Kano, ni awọn ọlọpa mu de iwaju adajọ.

Nigbat w ọ n ka ẹsun rẹ fun o fesi wipe, lati bi ọjọ mẹta ti on ti j a d e kuro n i n u ọgba ẹwọn on ko ri olurannlọwọ kọkan ebi inu si npa on beni aiyo onjẹ ni on nri jẹ l'ọgba ẹwọn ni on ba ṣe kuku lọ ja'le ki on le tun p a d a si inugbe on (Ọgba ẹwọn).

Adajọ sa si ẹwọn oṣu mefa Salawa bu ẹrin o si w i p e "Nagode Mcaida" Mo dupẹ o, ogi. O tilẹ fẹ doole ki ọlọpa kan to fa aide, bi nwọn ti nmu lọ beni o nsọ wipe awọn ko jẹki on dupẹ fun adajọ.

## Oloye Rotimi Williams Nilu Oyinbo



Ẹniti a nwo ninu aworan yi ni Oloye Rotimi Williams ti o je Minister of Justice and Local Government fun ijoba Iwọ Orun Nigeria, nigbati o dakan lọ silu Oyinbo lo ba Oludamoran (Region's Adviser) ijoba Iwọ-Orun sọrọ nipa iwadi ibẹru awọn ilu kekeke (Minorities Commission)

Oloye Major Tufton Beamish ti o je ọkan ninu awọn Igbimọ tu l'o nki Oloye Rotimi Williams ti o si gba l'Ejọ sinu Ile igbimọ na.

## Federal Welfare Department To Move To Kakawa Street.

It is hereby notified for the information of the general public that the Headquarters of the Federal Social Welfare Department together with the Youth Club Section and Port Welfare Section will move from the buildings of the Medical Headquarters into No 27, Kakawa Street, near Barclays Bank, Lagos on Monday, 19th May, 1958.

A. IZZETT

Chief Social Welfare Officer

### ILE AIYE TI JỌ
(O bere loju ewe kini)

Okotie-Eboh lo se nile Amerika ati nilu Gesi fun ilosiwaju ati idagba-soke Nigeria.

Ile aiye ti jọ fun wa,
Owo titun l'a nna,
Ko se mani l'a nlo.

A tun gbo wipe ni ose ti o mbo, Oloye Okoti-Eboh yio tun ba awon to nro owo sile soro nipa owo sile titun fun ilu wa.

### Akiyesi Pataki

A fi eyi kede fun gbogbo ẹnyin Aṣoju Iwe Irohin wa nilẹ Yoruba, l'oke Ọya, nilẹ Ibo, l'ọke Okun ati nilu Oyinbo wipe ẹnikẹni ti ko ba fi owo wa ranṣẹ ki oṣu to pari ao kọ orukọ rẹ fun Lọya Eleti-Ọfẹ, ao ba ṣe ẹjọ ao si gba owo irin ese lowo re.


## Freehold Houses For Sale

ITIRE ROAD ESTATE
SURU-LERE

NEWLY BUILT DETACHED FREEHOLD HOUSES
(THREE AND FOUR ROOMS)

**Prices From £1,520 (semi-detached)**

OVER HALF THIS ESTATE HAS NOW BEEN SOLD
INSPECT SHOW HOUSES ON SITE
REASONABLE MORTGAGE TERMS
ARRANGED
FULL DETAILS FROM:-

**Lagos Executive Development Board**

(ESTATE DEPARTMENT)
RECLAMATION ROAD, LAGOS.
TELEPHONE; 20384



### ERỌ ATATA TI NGUN IRESI TO SI NFE MỌ TONITONI
(Arcemill)

Ẹro na r'run lati lo, o si nṣe ise losegbadun; o to gbẹkẹle, o yayi, iṣẹ rẹ si buaiya.

Lese ese lo ba ti da iresi onifanda si, ni yio g'nu ti yio fe e, ti yio sọ ọ di funfun lau au.

LEVENTIS MOTORS LTD.
(Technical Dept)

Ebute Metta, Ibadan Kano, Port Harcourt ati Aba ni ẹ ti le ra ra.


### ONIFADE AJANAKU JOYE TITUN

EKO. Lojo keji osu April 1958 ni awọn fi Oluwo Onifade Ajanaku je oye Adele Alaga Ogboni Ibilẹ Nigeria ninu ile re ni No. 53, Okepopo Street Lagos

Ọpọlọpọ ese awọn enia pataki-pataki lo peju sibe awọn enia bi Alimi Oluwo Ogbogbo Segesege Asimowu iy. Idi aba, Apena sule Apena Taiwo, J. O. Ajoṣe S. F. Mobolaji Sodolanu Bale V.H, Anthony Abebi Ajanaku Jolade iya Alaje Adeoba Ologboni T.O. Afunsọ M. Mafe, Ewetuga Bale Ledi.

Basegun fi ebun nla ranṣe si Oluwo na ati Ayinke Daniel. Oloye titun yi fi jije ati mimu te gbogbo enia lọrun Inawo ati eye ọjọ na le gongo. Irohin ko to afojuba Oye na a mọri o.




### ARADAN NERVIGORA

Oogun ẹjẹ pataki fun imarale agba ati arẹmọ pipe fun awọn alaya pupọ. O dara fun inarun, ẹjẹ dudu, iṣokun oju, gbigbọn ọwọ, ailesun, ailokun ninu ati irufẹ arun bawọnni. O jẹ ajidewe fun awọn ti agbara wọn ndinku. Oo na gan ni ọkunrin yi lo ti o fi di "Afọṣẹ kun bi ojo." 5/6d. pere pẹlu owo ọkọ 1/d e.ç. 7/- Post Free.

The Egba Trading Aradan Stores 6112, Denton Street, 18, Denton Bridge Street, P. O. Box 2. Ebute - Metta. Phone 44153. A tun wa ni New Motor Park (Ogunpa) Ibadan.


Printed & Published by The Union Printing and Publishing Company 28, Kosoko Street P.O. Box 467 Lagos Phone 23370